

SEE YOU PAY THE
CORRECT PRICE.

ELETI OFE
A-NJU-WỌN KO SE WI L'EJO


AWOGBA
Omode fun
Girl, Boi,
Hihu - ehin,
Orere,
Ro Tire Ni
Ile Egbogi
— ISE —
Oladunjoye
Okebola,
Ibadan.
116, Great
Bridge St
LAGOS

VOL. No. IX 521. ELETI - ỌFẸ LAGOS, SATURDAY, MAY 25, 1957. KỌBỌ MEJI (2)

# Eto Akoso Ilu Bere Ni Ilu Oyinbo

LONDON Ni ijẹta eyiti ise ijọ Alamisi ni a bẹrẹ eto akoso bi ao ti ma se ijọba ilu Naijira si n i olu ilu Gẹsi ti a npe ni Londọnu ni a bẹrẹ e t o akoso na; ẹniti o si se alaga na ni Ọgbẹni Alan Lennox Boyd, akọwe ijọba fun awọn ilu ti o wa n i abẹ asia Gẹsi.

Alaga, Ọgbẹni Lennox Boyd ninu ọrọ ti o fi si ipade na o ni inu on dun pupọ lati ri pe a w ọ n ara Naijiria lọtun losi ti mura giri, awọn papa tilẹ ti mọ bi a tilẹ mu ofin ilu sẹ. Wọn ti mọ bi a ti se papọ se ilu ati lati da abo bo awọn mẹkunnu. Ọrọ ti on papa gẹgẹbi alakoso ipade na ko nipọ ju wipe ki on feti silẹ ki on si tun ba wọn ji roro.

Lẹhinti Ọgbẹni Lennox-Boyd ti sọrọ tan ni awọn alakoso ilu Naijiria mẹtẹta, Sardauna ti Sokoto, Oloye Awolọwọ ati Dokita Azikiwe, tun gbe lẹsẹ.

Ipade na a, bẹrẹ iṣẹ wọn ni kikun lọsẹ ti a fẹ bọ si yi.




# Kilose ti won fi nsa fun Sosi?

Ọkan ninu awọn okawe wa lati ilu Aganyin (Gana) lo ni ọrọ kan ti ngbe on lọkan tipẹ nipa a nlọ ṣe ihin nile Ọlọrun (ti a npe ni Ṣọṣi) wipe ki lo ṣe ti a k o nfi tẹdun tẹdun lọ mọ.

Ọrọ na ko mu ija lọwọ, ẹ ka, ki ẹ si jẹ ki a gbọ tiyin.

ỌRỌ NA NIYI

Olotu,

Boya ọrọ ti mo fẹ bere lọdọ awọn ara ilẹ Naijiria ati Gana, jake j a d o ilẹ Afrika le da bi afojudi, ẹ jọwọ kẹ fi ori jiemi, Ibere mi nipe ki lo ṣe ti awọn enia fi nsa lati lọ Si Ṣọshi ?

O to ọdun mejila nisisiyi ti mo ti fẹ b e r e ọrọ yi lọdọ awọn ara mi ti a npe ni Kiriyo (emi na si jẹ ọkan ninu wọn) ṣugbọn aye isinsinyi ki ṣe aye mọ gbagbọ-aye igbagbe ni.

Mo lọ sile isin ola kan ni sipẹ yi nilu kan ti gbogbo wa fẹ le sọ wipe on ni baba igbagbọ. Gbogbo ijoko ti mo ba nibẹ ti wọn pa ale le (ti nwọn fi orukọ le lori) ni a ko ri ẹnia n i b ẹ. K i l o f a ? Wọn ni Ọlọrun isinsinyi kole awa ti O da ni a bu ata sọwọ lati ṣe jamba fun arawa. Bi o ba ba ki o pa. bi o ko si ba ki o bu lẹsẹ pọ ninu ọrọ wa.

Mo ka Bibeli mi; wọn ni ibukun ni fun ọkonrin na ti ko joko nibujoko awọn ẹlẹsẹ. Awọn obinrin nkọ? Ọpọlọpọ nkan ti o sọ aye di ruduruda awọn lo fa. Aṣọ loku ti wọn nlọ fi han ni Ṣọṣi. Ibere mi niyi o mo nfẹ esi.

Emi ni

Simioun Aralamọ

**Lagos Executive Development Board**

ETO IJTUN ILU EKO ṢE

**IKILO**

FUN AWỌN ONILE ATI AWỌN OLUBAGBE

O lodi si ofin fun awọn ti o ba ti ko kuro ninu Ile lati tun gbe ibẹ pada. Ẹniti o ba si ṣe bẹ ao le jade lairotẹlẹ.

O si tun lodi si ofin fun awọn Onile lati fi awọn Yara ti o ba ṣofo fun awọn ẹlomiran ki wọn si gba owo-ile lọwọ wọn.

J.W. Henderson
CHIEF EXECUTIVE OFFICER

Reclamation Road,
Lagos.

# Irohin Ibadan

Lati ọwọ ELETI ỌFẸ

IBADAN. Ọrọ ti a pe ki baba ma gbọ, ni ọrọ ilẹ ẹlẹgbẹrun mẹrin pọun ti awọn diẹ ninu ẹbi ARẸ LATOSA ta fun Ijọba iwọ orun, lati fi se ebute ọkọ ofurufu (aerodrome) nilu Ibadan. Awọn kan sọ pe owo ti wọn gba na pọ si'bi kan, ko tilẹ kan awọn lẹnu rara. Wọn fi le ogun wọn fi lọgbọn; Olubadan Ọba Akinyẹle ba wọn da si wọn ni a fi bi awọn ba gbe de ibi ti o kuta dunlẹ. O di ọran kọtu giga.

2 Eleti Ọfẹ gbọ wipe, awọn agbagba bi Tafa Arowolo Arẹ ati oloye Agbakin Balogun Aminu Arẹ ti fi suru si ọrọ na wọn ni ki lọya awọn sọ fun adajọ wipe awọn yio se ni ọrọ ọmọlẹbi. A si ti fa iwe ẹjọ yi ya.

### Ọna Titun De

3 Irohin kan Eleti-Ọfẹ wipe Ọgbẹni Adelupọ Ogunmokun ti awọn Ijẹsha sọ wipe awọn afẹ ni Ọba awọn ti wọn si fi iwe ranṣẹ, Ibadan ni Ijọba iwọ orun si ti fi ọwọ si iwe rẹ. Ni aipẹ yi Ọba Ogunmokun yio ṣe iwuye.

Kabiyesi ade a mọori o! Awe, Eleti-Ọfẹ ni k'ọmọ gbagbe lati m,ọgọrọ ko mi li be e.

### Ori Rere

4 Ni agogo meji ọsan oni, Eleti Ọfẹ papa aba ~wọn lọ sibi iwe orire l'Ọke Mapo ti wọn fẹ ta Ewu ẹtu ri ma wọ nitoripe emi lo kan lọtẹ yi.


# ILE MBE FUN TITA NI Suru - Lere
## LATI £1250 SI £1600

Ẹniti e ba fẹ lo ra awọn ile na si danlẹ tabi ki o ma da owo rẹ san diẹdiẹ bayi :-

Ẹniti o ba ra ile oni adọta le lẹgbẹfa Pọun (£1250) yio san asansilẹ adọta-lerugba Pọun (£250).
Ẹniti o ba ra ile ẹlẹgbẹjọ Pọun (£1600) yio san asansilẹ irinwo Pọun (£400)
Oluwa rẹ ni lati san owo ti o ṣẹku tan larin ọdun mẹdogun (15 years)
Ẹniti owo tirẹ ba ṣẹku ẹgbẹrun Pọun (£1000) yio ma da san ni Pọun mẹwa-mẹwa. (£10) loṣoṣu
Ẹniti owo tirẹ ba ṣẹku ẹgbẹfa Pọun (£1200) yio ma da san ni Pọun mejila ati ṣile kan (£12 1/-) loṣoṣu.

Wọn o kọ gbogbo awọn ile na ni abẹ abojuto igbimọ L.E.D.B.

Ẹ kọ kọ kọwe si:-

NIGERIA BUILDING SOCIETY
5, Customs Street
P.M.B. 2078
Lagos



**Polowo Oja Re Sinu Iwe Irohin Eleti Ofe**



# LAGOS RACE CLUB
## JUNE MEETING
### Saturdays 8th, 15th 22nd and 29th June, 1957.

**FIRST DAY**

| | | START |
|---|---|---|
| RACE No. 1 | Five Furlongs Handicap Bottom Division | 3.00 p.m. |
| RACE No. 2 | Five Furlongs Handicap Bottom Division | 3.35 p.m. |
| RACE No. 3 | Seven Furlongs Handicap Middle Division | 4.10 p.m. |
| RACE No. 4 | Seven Furlongs Handicap Middle Division | 4.45 p.m. |
| RACE No. 5 | Seven Furlongs Handicap Middle Division | 5.20 p.m. |
| RACE No. 6 | Seven Furlongs Handicap Middle Division | 5.55 p.m. |
| RACE No. 7 | THE QUEEN'S OWN NIGERIA REGIMENTAL STAKES Eight Furlongs Handicap Top Division | 6.30 p.m. |

**SECOND DAY**

| | | |
|---|---|---|
| RACE No. 8 | Four Furlongs Handicap Bottom Division | 3. 00 p.m. |
| RACE No. 9 | Four Furlongs Handicap Bottom Division | 3. 35 p.m. |
| RACE No. 10 | Ten Furlongs Handicap Middle Division | 4. 10 p.m. |
| RACE No. 11 | Ten Furlongs Handicap Middle Division | 4. 45 p.m. |
| RACE No. 12 | Polo Scurry | |
| RACE No. 13 | THE SIR ADEYEMO ALAKIJA MEMORIAL PRIZE Six Furlongs Handicap Top Division | 5. 20. p.m. |
| RACE No. 14 | Open Race — Seven Furlongs Top Division A | 6. 30 p.m. |

**THIRD DAY**

| | | START |
|---|---|---|
| RACE No. 15 | Six Furlongs Handicap Bottom Division | 3. 00 p.m. |
| RACE No. 16 | Six Furlongs Handicap Bottom Division | 3. 35. p.m. |
| RACE No. 17 | Five Furlongs Handicap Middle Division | 4. 10 p.m. |
| RACE No. 18 | Five Furlongs Handicap Middle Division | 4. 45 p.m. |
| RACE No. 19 | Five Furlongs Handicap Middle Division | 5. 20 p.m. |
| RACE No. 20 | Five Furlongs Handicap Middle Division | 5. 55 p.m. |
| RACE No. 21 | THE NIGERIA DERBY Twelve Furlongs | 6. 30 p.m. |

**FOURTH DAY**

| | | |
|---|---|---|
| RACE No. 22 | Nine Furlongs Handicap Bottom Division | 3. 00 p.m. |
| RACE No. 23 | Six Furlongs Handicap Middle Division | 3. 35 p.m. |
| RACE No. 24 | Six Furlongs Handicap Middle Division | 4. 10 p.m. |
| RACE No. 25 | Six Furlongs Handicap Middle Division | 4. 45 p.m. |
| RACE No. 26 | Six Furlongs Handicap Middle Division | 5. 20 p.m. |
| RACE No. 27 | THE CORONATION PRIZE Ten Furlongs Top Division | 5.55 p.m. |
| RACE No. 28 | Open Race — Ten Furlongs Top Division A | 6.30 p.m. |




# Ero Mekka yio sanwo ori

IBADAN Irin ajo Mẹkka ọdun ni, Eleti – Ọfẹ gbọ wipe ko i i jẹ akanti, owo ọpọlọpọ ni yio na ẹniti Mẹkka ba npe, nitori ogun tabi ede-aiyede ti o wa larin awọn ara Misina ati Gẹsi pẹlu Faran nipa odo itọ Sulẹsi.

Iwe ti a ri gba lati ọdọ Ijọba Mẹkka sọ fun wa lati gba awọn Musulumi ilu Nijiria ni alejo, ṣugbọn ki wọn mura lati san owo ori Ijọba Saudi Arabi a ti awọn lọhun.

Aṣẹ is'ro gbogbo owo yi, o nlọ ti bi pọun mẹji o le ni ogun(£22).

Owo ori ilu Ijọba Saudi £5. 6/ owo Sambukia iyẹn jẹ £5. 8/; pọun mẹwa (£10) kan ẹwẹ a ni lati san silẹ fun atikọja ni Jidda ati ilu ti a npe ni Suakin – ki a maṣe gbagbe pọun kan owe ibusọ ni'lu Jidda.

Awọn Larubawa tun ni ki Eleti Ọfẹ tun sọ si etigbọ yin wipe awọn ko fẹ nkan owo siṣe ninu ẹru yin ju onjẹ ti ẹ fẹ jẹ lọ.

Ninu awọn enia pataki ti yio lọ si irin ajo Mẹkka na lati iwọ oorun nibi ni Ọlọla D ude S Adegbenro, Minista nipa ọrọ ilẹ ati ibi-isẹ.

# Igbeyawo ona ti Musulumi

Nigbati ọkunrin kan ba ti lọrọ pọ pẹlu wundia kan lati jẹ tọkọ taya, ọkunrin na yio rohin fun awọn enia rẹ wipe, on ti ba ọmobinrin kan lagbaja ọmọ tamẹdu ni adugbo bayi-bayi sọrọ, o si ti gba lati fẹ mi nitorina, ki ẹ lọ tọrọ rẹ fun mi. Nigba mẹta ni nwọn o tọrọ obinrin na.

(Wo yoku leju ewe kẹrin)

# Akeredolu Ale



Opolopo ninu awon agbe ti o mo ogbeni ti a npe ni Akeredolu Ale, ko ni le gbagbe ise rerere ti Ologbe na ti se si arin meji awon egbe agbe. On lo gbe awon de ipo ti nwon wa loni Nigba atijo ri, iye ti awon agbe nta iwon (Ton) koko kan boya In taye Poun mewa, Nisoju ologbe yi ni iye iwon koko se ga de Igba Poun (£200) fun iwon kan, Oloye Awolowo lo gbe owo koko na ga de Ogoji lerugba Poun (£200) Latigba ti Ologbe Akeredolu Ale ti salaisi, awon agbe koiti tun ni akowe ti o dabi re. Olorun ko dele fun, Nigba aiye re gbogbo awon agbe ni ko bi kita lati se ogbin Paki, Agbado, ere e, ati isu, eso Koko ni kan ni nwon gbajumo bi b· si [illegible] Iwo orun boya nse ni iyan ibe [illegible] Sunre, Akeredolu sunre.

# Olowo



Ninu iwe irohin wa ti ose to koja aworan ti a fi si be ko nse ti Ọlọwọ, Eyiyi ni aworan Ọlọwọ gan, Ki Kabiyesi forijji wa.

# ELETI QFE

A-NJU-WQN KO SE WI L'EJQ

EDITORIAL OFFICE & WORKS 28, Kosoko Street, Lagos P. O. Box 467

CABLES & TELEGRAM "ELETI - QFE LAGOS" Phone 23370

VOL IX, NO 521. LAGOS, SATURDAY MAY 25. 1957


## A nju wqn ko se wi lejo, ija ilara ko tan boro

Owe oke yi, ni a fi je omi toro qrq sinu iwe irohin wa, lose yi. Bi e ba si nwo oju awqn iwe irohin wa losese, bakanna ni eo ma ri owe yi ti a fi sibe, ko wa ni be lasan.

Awqn owe na ko wa nibe lasan, o ni idi ti a se nfi awqn owe na se ategun qrq. Anju wôn ko se wi lejq, beni ija ilara ko ntan bqrq. Bi o ti wu ki ori kadara Qlqrun ko ni pada.

Owe qse yi je ti awqn oniwa buruku, awqn keni mani enia ti o je wipe, losan ati loru gegebi ti qmq eni keji wqn yio se baje ni nwqn o ma wa kiri, sugbqn nwqn ti wa gbagbe wipe ibaje ti enia ko yi kadara Qlqrun pada.

Nitorina a fi eyi be enyin qkawe wa wipe ki e se atilehin fun wa lati ma se ikilq fun iru awqn enia ba wqnyi wipe "Wompari kan ko si, eniti o mmi kukute ara re lo nmi. Ara wqn ni nwqn nse.


E Ma Ka Iwe Irohin Eleti-Ofe Fun Irohin Aladun Ki E Si Ma Polowo Oja Yin Sinu Re



IMORAN FUN ENYIN ABIYAMO

Enyin abiyamq ewa ra QMORELA o dara pupq fun awqn qmqde.

Ama je ki omode ri orun sun daradara o dara fun otutu, ikq ati orisirisi arun miran ti o ma mba omode ja ni asiko ehin. Opolopo abiyamo lo ti lo egbogi yi fun omo won ti won si so wipe odara pupo fun awon omode

OMQRELA BABY MIXTURE

(SILE MEJI ABQ 2/6d. FUN IGQ KAN)

O wa lqdq :—

COMMERCIAL MEDICINE STORES

(Qualified Chemist)

19 VICTORIA STREET, LAGOS


## Lord Liverhume



Eniti a nwo ninu aworan yi ni Lord Liverhume ti o nse oluwa ati Olotu Ile isowo U.A.C. on na lo ni owo ti nwon fi ko aragbabu ile nla kan sinu ilu Ibadan University ti nwon npe ni Trenchard Hall. On yi kanna lo gba awon enia ti o lo se eto ominira nilu oyinbo ni alejo Eniti a nwo yi je olowo arakuyamu kan nilu Oyinbo, ti o je wipe nse lo kan ngbo pe on ni owo ninu Banki, sugbon ti ko mo pataki iye ti owo na je.

### IGBEYAWO ONA TI MUSULUMI

(O bere loju ewe keta)

Nigbati nwqn ba daje iyawo, awqn qbi ni di iya ati ti baba, olukuluku yio ko awqn qre re lehin lati wa ba se di yawo na. Eniti o nse iresi, qka, qbe, Dundun, dodo oniyeri, Pqfupqfu, Jqlqfu, ebe, ati orisirisi onje ilu yio ma dun lqtun losi lqjq iyawo, enia yio pq bi omi.

Qkq iyawo yio mu Poun mefa, mewa tabi ogun Poun gegebi on pelu iyawo ba ti sq si owo Baba gbq iya gbq owo awqn obinrin ile, owo awqn qmq ile igo oti, igo oyin, erogbe Adun ati obi yio gbe lq sile iyawo gegebi.

Lehin ti nwqn ba ti gba gbogbo nkan awqnyi tan, nse ni nwqn ma soyigi nigbati ile ba si su, awqn mu iyawo lq sile qkq.


No 69.

# Federal Education Department

## Lagos Education Office.

VACANCIES FOR TEACHERS GRADE III

Applications are invited for two posts of Teachers Grade III in the Education Department. Particulars in Government Notice No. 866 in the Federation of Nigeria Official Gazette 25 Volume 44 of the 16th of May, 1957. Application to Secretary, Federal Public Service Commission, Private Mail Bag No. 2586, Lagos Closing date 15th June.



SIR JAMES ROBERTSON

# Governor General

Ẹsiti a nwo aworan rẹ yi ni ọlọla Sir James Robertson ti o nṣe Governor General fun ilu Eko. On lo lọ si ibusọ ọkọ Ofurufu nigbore ilu Kano, lẹhin na ni on pẹlu iyawo rẹ ba ọkọ ofurufu fẹlọ silu Oyinbo, fun eto ominira ilẹ Nigeria. A gbọ wipe odidi wakati meje ni ọkọ rẹ fi pẹ lẹhin ki o to de. Oloye Awolọwọ Oloye Okorodudu Ọgbeni Mbu ati Malam Maliki lo lọ pade re ni ibusọ ọkọ ofurufu silu Oyinbo.

# Adura fun Ominira

Inunurin awo Inunurin, Alakiaṣa awo Ilaṣa. lo difa fun Alayun ayunrẹ ti gbogbo aiye rin gbindin-gbindin mọ o wa to gẹ ki a gba ominira niIẹyi Gbaja lẹja yio ma yọ mọ wa Gbaja Ire ko lorakọ meji ire ni ire njẹ gbogbo ara ni kẹfun-kẹfun fi okun ajẹ Ogbe-ire

# Oriu Omode

Mo ba abere lori odo mo ba osusu lehin owo, bi o ko ba tete k'eru re, ma fi ewure bo Ifa ngo fi aguntan bo ole, alamu goke lo, obimo, kobimo, obimol'atalugba, okan nje were-ke, okan si nje wereke, okan nje ku'kute arumo o fi ori la apata. Jebire -jebire, pata - ara pata -ara o gbemi l'agada iroko iroko iroko




*Family links with*

**THE UNITED AFRICA COMPANY LIMITED**

*Recording some of the many families who have found interesting, varied and worthwhile careers with The U.A.C.*

THE OSORI family have a wonderful record of over 360 years' service with the Niger River Fleet! It began in 1888 when Yakubu Osori, a canoe puller, joined the Niger Company as galley boy. He gained many promotions and retired in 1941 with the rank of Captain — a distinction also attained by seven of his kinsmen. The present head of the family, ex-Commodore Momodu Osori, served 54 years before retiring in 1948. Fifteen members of this family have made careers with Niger River Transport. This strong link, unbroken for 69 years, gives the Company great satisfaction.

**The Osori Family**





H37A

Members of the Osori family who served with Niger River ...

... 53 years
Momodu Osori, 54 years
... 37 years
... 29 years
... 33 years
... 20 years

Members of the Osori ...

Kadiri ...

Our pictures show some of the Osori family working for the Company

# Eniti o ba dale, ile yo da san

Lati ọwọ
MODUPẸ ODUTỌLA

Nigba atijọ, Ọkunrin kan wa ti orukọ rẹ njẹ Ojo o si ni iyawo kan ti o njẹ arẹwa, ti orukọ rẹ njẹ Lukata Iṣẹ ti Ojo nṣe ni iṣẹ aṣọ hihun lori apasa.

Li ajọ kan awọn aladugbo Ojo wa ṣe ofofo fun wipe Lukata orin rin ti ko dara larin ilu, ṣugbọn Ojo da wọn lohun pe, ẹgbọ tara yin Bẹni Ojo ndojuti gbogbo awọn enia ti wọn ba wa ṣe ofofo fun. Lẹhin eyi laipẹ wọn fi Lukata jẹ Iyalode ilu. O si wa ṣe o bẹrẹsi mura lati wuye. O ranṣẹ si Ọba ati awọn Ijoye, wọn si fun ni Ikarọ eyiyi ni gbogbo ohun ti awọn Ebọra ati awọn enia yio gba.

Lakuta, ẹniti o ti ṣe iwa ilrju ati iwa aidara si ọkọ rẹ di gbajumọ nilu. Koṣeni, koṣeji o lọ ra malu ati awọn nkan orişirişi o ranṣẹ pe ọpọlọpọ awọn alase ki wọn wa ran on lọwọ nijọ ase. Wọn ṣe eto, eto si jọ.

Ojo ẹniti o mọ arekenda ati ọgbọn ẹwẹ iyawo rẹ, o dakẹ o si mu suru ko si ba ẹnikẹni sọrọ inu rẹ. Nigbati ọjọ ase ku ọla Ojo pe iyawo rẹ o ba da imọran wipe on ti lọ ṣe iwadi ọrọ iyanju wipe nigbati Iyalode ba ti se ase tan, ki wọn e ko gbogbo onjẹ sinu yara kan, ki wọn ti ilẹkun mọ on ọkọ rẹ pẹlu onjẹ ni yara. Lẹhin ti on ba ṣe etutu tan ki wọn o silẹkun. Iyalode si gba ọrọ ọkọ rẹ si otitọ.

Gẹgẹbi adehun, nigbati wọn se ase tan wọn ko onjẹ sinu awo nlanla omiran ninu awọn awo wọnyi dara pupọ ohun ti a le juwe. Wọn si ko onjẹ wọnyi si inu yara kan fun etutu. Nigbati Ojo fẹ wọle, o gbe igba pakata pẹlu ọmọri nla kan lọwọ rẹ o si ri ki awọn enia ti o wa nibẹ ma ba on kọfẹ.

Bẹni awọn enia bẹrẹ si wọ pe, Ọfẹ, Ọfẹ, Ọfẹ Nigbati a ti ilẹkun mọ Ojo pẹlu onjẹ, o bẹrẹ si onjẹ wọnyi wo lorişirişi Igba pakata ti Ojo gbe wọle, igbẹ ti ori atitan lo kun inu rẹ O bẹrẹ si fi igbẹ diẹdiẹ tẹlẹ iyan, elubọ ati awo ọbẹ pẹlu. Nigbati o ṣe eyi tan o şilẹkun o si jade o ni on ti pari etutu ti on nṣe tan.

Lẹhin eyi awọn omidan pupọ ti wọn wa ba iyalode ṣe ẹyẹ bẹrẹ si gbe ẹru awo onjẹ nikọkan wọn doriko ibiti atẹtafo si. Nigbati wọn de ibẹ, Ọba Ijoye ati gbogbo ilu peju, wọn to awo onjẹ gbogbo silẹ. Lẹhin eyi Iyalode pẹlu awọn obinrin nlanla ilu nwọn si mura jigbini, Şugbọn ki wọn o to de ibi atafo yi, Ọba, ati

awọn Ijoye ti bẹrẹ si jẹun Nigbati Ọba kan igbẹ ni isalẹ iyan o fẹrẹ bi ifun. Bakanna ni nigbati awọn Ijoye nkan igbẹ nisalẹ awo ọbẹ.

Bi wọn ti wa ninu rogbodiyan yi ni Lakuta ẹniti nwuye yọ lọkọkan. Bẹni Oloye Agba ẹniti iṣe adajọ ilu fun awọn Ọlọpa laṣẹ pe bi Lakuta ba ti de ibin nina ni ki a sa pẹlu bilala.

Bi Lakuta ti wọ gbọngan ti awọn enia gbogbo wa bẹni wọn ko bilala bo.

O fẹ mọ ẹṣẹ ti on ṣe şugbọn ọpọlọpọ bilala ko fun ni aye, nigbati ori wipe ọrọ na ko dara mọ, o fi igbẹ sọna, ere tete lẹsẹ Ole, Şugbọn awọn ọlọpa ko pada lẹhin rẹ titi o fi fẹrẹ de ile Ojo ọkọ rẹ.

Ojo ẹniti o ti mọ nipa ọrọ wọnyi bẹrẹ si wun aṣọ rẹ bi ẹnipe on ko mọ nkankan, o si bẹrẹ si kọrin wipe, "Laku ode ni ao ti ku ẹ wa le".

Oju ti Lakuta pupọ o binu o sure lọ bẹ sinu odo o si di ẹranmi ti a npe ni ese di ọjọ oni o.

Ẹniti o ba nhuwa bubaru yio ko ikore rẹ lọjọ kan. Eniti o ngbe inu okunkun ti o nşişẹ ika ti o sọ pe Ọba aiye ko ri ọo, bi ti aiye ko ri ọ nkọ, ṣe Ọba ọrun nriọ A ki igbin alubọsa ko hu ẹfọ, ohun ti o ba gbin ni ao ka. Olukuluku yio si jere iṣẹ ọwọ rẹ o.


## Kere o!

A ti ni orişirişi ogun German to ṣẹṣẹ de, fun oniruru aisan tọkunrin tọbinrin. Yete wa ra tirẹ k'o to tan.

**J. A. AJAO**

**BROTHERS**

MEDICINE STORES

7, Egerton Road, Lagos.


# Soja nkose Abese-kun-bi-ojo



Awon ti a nwo ninu aworan yi ni awon omo ile enia dudu ti o lo ko ise jagun-jagun nilu Oyinbo sugbon nwon tun fe ko ise. Abese-kun-bi-ojo pelu mo ise oguu jija.

Awon ti a nwo yi ni Saji majo Joseph Famiye enia dudu ati Saja Mejo Albert, nwon ndanra ese wo.

# Ebun asiko ojo niyi

## Wa je 375,000/- ninu

Orire ti S. C, L.

Enití o ba yege ninu orire na yio je 355,000/- enití ila kini ati ekeji tirę ba dogba po pelu tiwa yio je 20,000/-

| | | | |
|---|---|---|---|
| | | | |
| | | | |
| | | | |
| | | | |

șe eto awọn nomba lati 15 si 30 ninu ojule kokan, tobę ki aropo rę lati otun si osi, lati oke sisalę lati igun kini sisalę igun keji je 90, A ko gbędę

leki nomba kan po meji n'nu rę. Ojo ti a ko ni gba iwe lodo eni kan mo je 24/6/57.

E fi gbogbo iwe nyin ran ọkọ ofurufu. Esi rę yio jade ni 30/6/57.

| Last Result Total 82 | | | |
|---|---|---|---|
| 29 | 26 | 27 | 32 |
| 24 | 35 | 34 | 21 |
| 36 | 23 | 22 | 33 |
| 25 | 30 | 31 | 28 |

Owo eyọ kan 20/-. Fun mẹrin 40/- Fun merin dilogun 80/- Fun merin lelogun 100/- Fun meji lelogbon 120/-

OFIN:- Enití o ba fę șe pupo, le șe sinu iwe miran bi o ba fę Postal Order tabi Money order ni a fę Nomba ti Gesi ni a fę

enití orire tirę ba dogba po pelu tiwa ni so gba pe o yege
Enití o ba fę gbọ esi ki o fi 1/- owo ọkọ kun owo tirę
Șugbon bi o nfę kiakia fi 2/- owo ọkọ ofurufu kun owo tirę
Ko si ęjo sibę, eyi ti a ba șe ni abę ge.
Fi owo ati orire ti rę ranșę si.

**S. C. L. CORPORATION**

MANIK CHOWK, P. O. 12, ALIGARH CITY (INDIA)


# Odale! Odale Ba Ile Ku

Awọn opitan sọ fun wa wipe, ni gba aiye Oloye Taiwo Olowo, o ni ẹran agbo kan ti o ma nsin loju ode iga rę, lori iso na lo ti nfun ni onję.

Lọjọ kan ti oru mu dię, Taiwo Olowo bọ si ę sę iga lęgbę ile Owolabi ọmọ rę o si nfun ẹran agbo rę ni onję. Bęni ọkan ninu awọn ara isalę Eko nkọja lọ, bi o si ti ri Oloye Taiwo Oloye, o ya sọdọ rę lati ki.

Bi ọkunrin na ti mbọ lọdọ Oloye bęni ẹran agbo yi nwo o. Nigbati o ku sata ki o de ọdọ Taiwo Olowo, bęni o mori lọ silę lati dobalę ki Oloye, bi o ti ku dię ko fi igba aiya kanlę, nșe ni ẹran agbo na gba iwo le ọkunrin na ni agbari, o si șe yakata.

Oloye Taiwo Olowo dahun o wifun ọkunrin na wipe Ha!, odalę, eni dalę yio ba ilę ku. Nigbati Danmọle gbọ, on lo fi ọrọ na kọrin bayi pe:-

A gba to fę dọbalę
To wa fę Poloye lapata
Eni dagba S'abosi
S'abosi o
Ori ę lo fabọ si.

# Ilewe Giga ilu Awe Ni Oluko Pataki

AWE-OYO. The Awe High School ti o je ilewe giga fun ilu Awe gba awọn ajeji oluko meji laipę yi fun ilọsiwaju ilewe na. Oluko kini wa lati ilu Saro. oruko rę ni I.E. Davies ti o ti gba oye M.A. enikeji ni Ogbęni E.G. Ndudu, e iti o ti gba oye B. Sc Dip. Ed. ara ilę South Afrika.

Oloye J.A. Ajao pe gbogbo awọn ọmọ ilewe na jọ lati șe ęyę fun awọn oluko mejeji na. Ninu ipade na Il Ajao ti sọ pe, bi awọn ba tilę nsọrọ nipa awọn oluko ti o gbọn fafa, awọn ọmọ ilewe giga ilu Awę ni ętọ lati fi ogun oluko wọn titun meji yi gbari, pe, awọn ni oluko ti ogbọn fafa.

Ogbęni D.A. Odutayę ti o nșe Oluko agba ati Alufa Eni owọ, E.A. Atilade lo tun sọrọ nipa iyi ti wa ninu oye ękọ ninu iwe bi o ti niyi to, nwọn si mu ipade na wa si opin


Nje nwon fe gba bolu lose yi? fi egbogi ajebidan pa awon ibiti o ndun o



ELECTRIC Balm





# AWO REKODU 6/-

Wa ra awọn rękọdu ti o gbadun nwọnyi lọdọ wa:

1870. E s i ę r ọ nyin ; Lawani Akano - S. Aka.
1871. Ọmọ atiro ; Ọlanrewaju — ,,
1872. Abaniję ; Bisiriyu Kayọde — ,,
1876. Late Awoyęle ; Daniel Ọręyọmi - Ayinde Bakare.
1877. Late Ọmọșọla Savage ; Ọrę meji — ,, ,,
1878. L.O. Gbamgbala ; Sule Mayeto — ,, ,,
1884. A j ọ m ọ g b e ; Moronmabọ - Rio Lindo
1885. Late Ọmọșęla ; Jo Mambo — ,, ,,
1886. Olomo lo laiye ; Late Awoyęle — ,, ,,
1887. Sio lele ; Late Chief Thomas — ,, ,,
1902. Ogede Mbajẹ ; Eda ma tori awa da - Alabi Ewuro
1903. Igba mbajo ; Eleko Adisa. — ,, ,,
1904. Gbi ni mo gbọ ; Erinmi lokun — ,, ,,
1912. Aka șe mi lalejo ; Jubirala - Lamidi Ajeigbe
1913. Af'emi - af'emi ; Mo re mọ kan — ,, ,,
1914. Ma mowo ra ; Kinkin n i mi — ,, ,,
1915. Ọba ilo a i y e ; Mapaja — ,, ,,

Fi owo-ọkọ kun owo ọja ti o ba fę ra.

**Egba Trading Aradan Stores**

18, Denton Bridge Street,
P.O. Box 2, Ebute Metta.


No 70

# Vacancy

Applications are invited for the post of Higher Executive Officer, Federal Education Department. Particulars in Government Notice No. 780 in the Federation of Nigeria Official Gazette of the 2nd of May 1957

**IB JK JN N F N IRANTI ES R OLODODO**



Ni ọjọ 24 ti oṣu Mai 1957 ni Olo ba Lambi Thompson ti a nwọ n ti a ran yi yio di ọdun kẹrin ti o ti filẹ ṣo aṣọ bora.

Ninu awọn ọmọ to fi silẹ ni M. A. Thompson Bank Manager T. A. Thompson Editor Eleti-Ofe.

Bi ba maṣe je ikun, maṣe je ekolo, ohun ti awọn nje I iode orun ni ki o ma ba wọn ẹ. Sunre, Opomọ-ti-a-ckan, Sunre



**Anjorin Liniment**

Ideal for Sprains, Lunbago, Neuralgia, Rheumatism Sciatica Colic Pain, &c.

2s 6d

ANJORIN CHEMISTS Ltd. 116, King George Avenue, Yaba and Branches. Phone 44288.

## Lagos Executive Development Board

### ETO ATUNṢE ARIN ILU EKO

### YIYAN AYE FUN ILE OJA MIRAN

A si mba ilana Ile Wiwo lọ gẹgẹbi eto ti a ṣe ti o je pe awọn Ile ti o wa ninu ọkan ninu awọn aye Mejila ti a pin awọn eto ile wiwo na si lati yanju apakan ti a ti wo na ki a to ma ba ibomiran lọ.

Awọn Ṣọbu ti wọn nta ọja nisisiyi, ti ile wiwo yi si nṣe idiwọ fun nipa wipe wọn ko ri aye lati ma ba iṣẹ owo wọn lọ, nitorina a gba ni ero wipe ki a tete kọkọ fun awọn iru oniṣowo wọnyi ni aye siwaju igbati eto na gbo-gbo yio fi yanju ki o ma ba si idaduro ninu iṣẹ owo wọn.

Igbimọ yio gba fun awọn ti wọn ni Ile-owo Commercial Premises) ti ara wọn ninu ibiti ilana eto wiwo ile yi wa lati tun ko ile-owo miran si arin ibiti ati wo ki o to di igbati eto na gbogbo yo yori.

Awọn ti nwọn ni ile-owo ti ara wọn, ti iwe ile-owo na si je ti wọn (freehold) nikansoso ni arin ibi ilana eto ile wiwo yi, ti ile wọn si ju ọdunrin ọpa lọtun losi (300 sq. yds.), ti ile-owo na si je ti oluwarẹ fun iwọn ogun ọdun nikan ni ao yẹ iwe wọn wo fun eto yi.

Enikeni ti o ba fara mọ eto yi, ti wọn si fẹ lati tun ile-owo wọn ko, ti o si fẹ gbọ agbọye si nipa eto yi ki o wa ṣe abẹwo ni ile iṣẹ awọn igbimọ L.E.D.B. nibiti a o yẹ awọn ọrọ ti o ba mu wa wo.

**J.W. Henderson**
Chief Executive Officer

**Let's have MUSIC! HEAR THE LATEST HIT NUMBERS**



*Read this list of popular titles*

JZ 6077-Omosola Savage/Igba Laiye .. .. .. ..
,, 6078 Aiye Akamara/Iwa Rere Leso Enia
,, 6079-Gbo Adura wa baba/Irele Lo Laiye . . .
Rosey Show Mambo Orch )
,, 6080 Gba wa lowo Ota/Iberu Olorun-S.O.A.
Ladipo & His Koranic Group



JZ 6082-Olomo le Laiye/Feso Jaiye .. .. .. )
,, 6083-Shogbola/Wellington .. .. .. )
Ade-Ade & His (Juju) Orchestra )
,, 6088-Owo Lowo Agbara Ko/Abiba Alaso .. )
,, 6037-Ori Lo Yemi/Saka Ilorin .. .. ..)
Aminu Olaribigbe & His (Sakara Band)
,, 6089-A Gbere Wa De/Awon Kokokoko-Taibus Abu na & His (Apala) Band.

*Sold by all the best stores*

**"HIS MASTER'S VOICE" *yellow label* RECORDS**

THE UNITED AFRICA COMPANY OF NIGERIA LIMITED

Printed & Published by The Union Printing and Publishing Company, 28, Kosoko Street P. Box O. 467 Lagos Phone